Bibeli fun awon omode

# Ibi Jesu



Ikosile gba owo: Edward Hughes

Ayaworan: M. Maillot; Alastair Paterson

Olu'lo: E. Frischbutter; Sarah S.

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

©2023 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi, niwon igba ti o ko so di owo.


Laye atijo, Olorun ran angeli
Gabreli si omidan Israeli
kan ti anpe ni Maria.
Owifun pe, “iwo yio bi
omokunrin kan, iwo yio
sipe oruko
re ni Jesu.
Ao pee ni
omo Olorun
oga ogo.
Yio si joba
titi aye.”

"Bawo li eyi yio se ribe?" Omobinrin na wi. "Emi ko tii mo Okunrin kan ri". Angeli na so fun Maria wipe omo na yio ti odo Olorun wa. Ki yio li Baba eleran-ara.



Angeli na so fun Maria wipe Elisabeti arabinrin re pelu ti loyun li ogbo ojo re. Iyanu li eyi je, pelu. Lehin eyi, Maria losi odo Elisabeti. Won yin Olorun papo.



Maria li afesona ti ape ni Josefu.  Inu Josefu ko dun nigbati o mo wipe Maria ti loyun. O ro wipe okunrin miiran lo fun loyun.



Ninu isipaya, Angeli Olorun so fun Josefu wipe omo na je omo Olorun.  Josefu ni lati ran Maria lowo lati se itoju Jesu.





Josefu gbekele Olorun o si gboran si lenu. O tun gbo ofin ilu re. Nitori ofin titun, ohun ati Maria losi ilu betlihemu

lati lo san owo ori.



Maria se tan lati bimo. Sugbon Josefu kori ile nibikibi. Gbogbo ile ipamo li won ti gba tan.

Josefu pada wa ri ibuje-eran. Nibe, li abi Jesu si. Iya re gbe si ibuje-eran nibiti awon eran ti njeun.



Nitosi, awon Oluso aguntan nso agbo eran won. Angeli Olorun farahan won osi fi ihinrere iyanu na fun won.




“Abi fun yin loni n’ilu Dafidi Olugbala ti ape li Kristi Oluwa. E o ri omo na ti afi oja we odubule si ibuje-eran.”


Lojiji, opolopo Awon angeli alarabara farahan, won fi ogo fun Olorun wipe “Ogo fun Olorun li oke ati
aiye alafia, ife inu rere si gbogbo eniyan”.


Awon Oluso agutan losi ibuje-eran.
Lehin igbati won ri omo na won so
fun gbogbo eniyan ohun ti angeli
na so fun won.



Lehin ogoji ojo, Josefu ati Maria gbe Jesu wa sinu tempili li Jerusalemu. Okunrin kan wa ti ape li Simeoni, fi iyin fun Olorun fun omo na nigbati Anna woli agba, osise Oluwa miiran dupe.



Won mo wipe Omo na je omo Olorun, Olugbala ti ase ileri re. Josefu fi eiye meji se irubo. Eyi li irubo ti ofin Olorun so wipe ki won ose nigbati won ba gbe omo titun wa si odo Oluwa.



Lehin Igba kan, Irawo kan fi ona han awon okunrin

ologbon lati ile ila-orun si Jerusalem. “Nibo li omo na ti abi li oba awon Ju wa?” Won beere. “Awa lati wa sin.”

Oba Herodu gbo nipa awon ologbon okunrin na. Okan re po ruru, o wi fun won pe ki won so fun ohun nigbati won bari Jesu. “Emi pelu fe sin” Herodu wi. Sugbon eke li eyi. Herodu fe pa Jesu.




Irawo mu awon Ologbon okunrin na losi ile ibi ti Maria ati Josefu ngbe pelu omo na. Won wole lati sin, awon aririn ajo na fi ebun fun Jesu, fadaka ati ohun oloorun didun.

Olorun so fun awon ologbon okunrin na lati pada sile loni bo nkele. Inu bi Herodu gidigidi.



O pinu lati pa Jesu, eni ibi na pa gbogbo awon omokunrin li Betlihemu.




Sugbon Herodu kolee se omo Olorun ni ibi! Pelu ikilo loju ala, Josefu gbe Maria ati Jesu losi Egipiti.

Nigbati Herodu ku, Josefu gbe Maria ati Jesu pada wa



lati Egipiti.
Won gbe nilu kekere kan ti ape ni Nasareti, leti okun Galili.

Ibi Jesu

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Iwe Matthew ori kini si ori keji,
Luku ori kini si ori keji

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi 119:130

Opin

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe otito ni eyi, so fun Olorun wipe: Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi, osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo! Johannu ori keta ese kerindinlogun.